## ILU ẸSA-OKE NFẸ ATUNṢE

(Lati Ọwọ Josẹ Ọla. Ọlalẹyẹ Ebute Mẹtta.)

Inu mi yio dun ti Oletu Irawọ Obokun ba le gba mi laye diẹ ati sọrọ nipa ilu Ẹsa Oke gẹgẹbi Ogbeni Adedeji ti fihan gbangba niwọn ọrọ re pe ilu Ẹsa Oke nfẹ atunṣe papọpupọ. Mo ki Ogbeni Adedeji pe o ṣe pupọ atipe Ọlọrun yio jẹki ile Olumọjo na kio gbo e.

Saju ọrọ mi, mo ki awọn ọmọ Ẹsa Oke ni ile ati loko pe o to akoko fun olukuluku wa lati ji giri si atunṣe ilu Ẹsa Oke nitoripe lati nkan bi ọdun mẹwa sẹhin tabi jubelọ ni ilu yi ko ti ni ilọsiwaju bi awọn ilu miran ni agbegbe Ilesa. Kini o fa, ki iṣepe a ki da owo ori wa, ki isi ṣepe a ko ni enia fun ilọsiwaju ilu yi, sugbọn idi patаki nipe ilu yi ko ni Ọba atata.

Sugbọn nisisiyi a dupẹ lọwọ Ọlọrun pe ilu yi si ti ni Ọba ti o ba igba ati akoko ti a wa yi mu, Nitorina mo mọ dajudaju pe ti omi tuntun ba de dandan ni ki ẹja tuntun wọ inu rẹ. Laiṣe aniani, inu mi yio dun ti awa ọmọ ilu Ẹsa Oke nile ati loko ba le mura gidigidi fun ilọsiwaju ilu wa. Nitoripe ẹlẹtu lo ngbe ẹru rẹ ni awọn enia le ba kọfẹ mọ.

Lọna keji, mo ki awọn aṣoju gbogbo ninu Ijọba ti gbogbo Ijẹsa pe wọn ku eto ilu. Ọlọrun yio si jẹki ilẹ Obokun na kio dara fun gbogbo wa. Mo bẹ awọn aṣoju wọnyi pe ki awọn na papa fi oju inu wo iru ipo ti ilu Ẹsa Oke wa. O jẹ ohun itiju ati iyalẹnu gidigidi pe ilu yi ko ni ile ifiweranṣẹ (Post Office) bẹni ko si ile Iwosan fun awọn alaisan ti o nilari ni ilu yi.

Gbogbo ona arin igboro ilu yi ko si ẹyọ kan ti o ṣe gun keke rara. Bẹni ninu gbogbo ilu tio wa ni agbegbe Ilesa ko si ninu wọn tio saju ilu yi nipa dida owo ori wọn lakoko. Mo si inreti pe o *yẹ ki awọn ara ilu

Ẹsa Oke le ri anfani ti Ijọba ṣe fun wọn ninu owo ori ti wọn nda lọdọdun. Sugbọn dipo pe ki Ijọba ṣe anfani fun ilu yi, ṣe ni wọn gbagbe ilu na patapata lati bi ọdun mẹwa sẹhin. Nitorina ẹnyin alaṣẹ ilẹ Ijẹsa, ilu Ẹsa Oke tọ fun abojuto. Awọn enia wọnyi na nfẹ ọna tio dara larin igboro bẹni wọn si nfẹ Ile Ifiwe ranṣẹ ati Ile Iwosan tio nilari ti ki iṣepe enia ma debọ ti alabojuto ile iwosan (Nurse) kan ṣoṣo ti o wa nibẹ ma sọpe ko si egbogi fun iṣẹ rẹ lati ṣe.

Ki nto pari ọrọ mi, mo ki Lọja Ẹsa Oke pe ki ade pẹ lori ki bata si pẹ lẹsẹ. Iṣẹ gidigidi ni ọrọ ilu Ẹsa Oke. Ọlọrun tio fi ṣibẹ ko ni dẹra ba: Yio si ba ṣe atunṣe ilu na: Gẹgẹbi alaga Igbimọ ti Ẹsa Oke pẹlu awọn Kansẹlọ rẹ, ilọsiwaju Ẹsa Oke di ọwọ nyin e.

Mo si fẹ ki awọn Kansẹlọ wa fi oju inu wo iru ipo ti Ẹsa Oke wa si awọn ilu bi Iboken, Ijẹbu-Ijẹsa ati awọn ilu bẹbẹ. Mo si tun bẹ Ogbeni T. A. Babajide eniti o jẹ aṣoju ilu yi ninu ipade gbogbo gbo ni Ilesa pe ki o mura si ọrọ ilu yi gidigidi. Mo fẹ ki Alaga wa ati awọn Kansẹlọ rẹ mọ daju pe awa ọmọ Ẹsa Oke nile ati loko wa pẹlu wọn ninu ohunkohun ti wọn le ṣe fun ire ati ilọsiwaju ilu.

Ni ipari ọrọ yi, inu mi yio dun ti awọn Kansẹlọ Ẹsa Oke ba le ṣe iwadi ọtadinnirinwo poun (£350) ti Ogbeni Adedeji fi ẹnu kan ninu ọrọ rẹ pe nwọn fun ilu yi fun atunṣe igboro ilu na. A fẹ mọ ibiti owo na wọlẹ si. Nitoripe ilu Ẹsa Oke nfẹ owo pupọ fun atunṣe ilu na ju pe ki owo ti o pọ to eleyi, lọ ba igi sibikan lọ.

Nitorina gẹgẹ bi a ṣe nireti ninu awọn Kansẹlọ wa tuntun wọnyi, mo ro pe awọn na yio [illegible]to lati wadi ọrọ owo na. Ọlọrun ko ba wa tun ilu wa na ṣe o

## AWỌN AFỌBAJẸ NI ILU ẸRINMỌ

(Bẹrẹ lati oju iwe 2)

fiye ipade na pe, ati awọn ti npe fi ara wọn ni idile afinijoye, gbogbo wọn lo fi Asede jẹ oye Ẹlẹrinmọ

Loyin Atapa sọrọ die pe, nigbati wọn mu Asede lọ si ile Ọwa awọn jijọ lọ sibẹ ni. O ni nigbati wọn de ọhun, Kabiyesi sọ bayi pe Risa Ẹrinmọ fẹ gba Asede lọwọ on ni, o dahun pe bẹni on fẹ gba.

Awọn ipade bi lere pe ewo ni o fara mọ o wipe, on ko fara mọ Owoẹyẹ ipade wa bi Risa Ẹrinmọ pe Ijoye ibo ni. Risa Ẹrinmọ dahun pe, ki iṣe ijoye ti Ẹrinmọ, Atapa ni.

Balogun sọ ọrọ pupọ pe awọn ti o pe ara wọn ni idile afinijoye Ẹlẹrin[illegible]

awọn ni o sọ oye wọn nu, Alaga sọ ọrọ pupọ o si fi aṣẹ [illegible] pe ki Ẹrinmọ lọ ṣe atunṣe ni[illegible] wọn, ki awọn o le pari ọrọ [illegible]wa. Ipari ipade na ni pe ki [illegible]nmọ lọ ṣe atunṣe ni ilu wọn. A bẹ ijọba Aiyepeju Council[illegible] wọn bani pari ọrọ oye Ẹlẹrinmọ. Ọwọ yin n[illegible] ọrọ na ku si [illegible]yin. Awa ọmọ Ẹrinmọ si nreti i[illegible]

AKỌLE [illegible]U:- A gbọ pe igbimọ A[illegible]ade ti wọn ṣe gbẹhin. Ẹlẹrinmọ [illegible]oyẹ Asede ni agbọ Ogbeni [illegible] na faramọ pe ki o jẹ wipe i[illegible] Ẹrinmọ.

## AKIY[E]SI

**FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGB[Ẹ] NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ**

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgb[ẹ] [illegible]NC mọ pe ipade ọjọ [illegible]ay ko yi pada: nitorina mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni We[illegible] lati ma wa si gbogbo ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi s[illegible] ipade dede.



ỌGBẸNI E. D. ADEDỌJA

On ni ẹniti o tijẹ olori awọn olukọ ni Oke Oye ri. A gbọ pe o tidi Olubẹwo nipa eto ikẹkọ fun ilewe ijọ Aposteli ti Oke Oye.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"


OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 7s. | ,, ,, ,, |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 4s. | ,, ,, ,, |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | [illegible] | ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | ,, ,, ,, |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 5s. | ,, ,, ,, |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JẸ OWO KANNA

PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## GBA ẸMI RẸ LA NI IJỌ KERUBU.

Lati Ọwọ Sunday Ọmọle AY. 14.

Iuu mi iba dun bi Olotu Irawọ Obokun ba le gba mi laye lati sọrọ sinu iwe Oloyin mọmọ yi.

Ni Ijọ Kerubu Serafu, Ọlọrun gbe awọn iranṣẹ mẹta kan dide nibẹ lati ma sọrọ fun olukuluku gẹgẹ bi ọna rẹ ba ti ri. Ọrọ na ga pupọ. Iṣẹ Ọlọrun awamaridi ni. Irohin ko to afojuba.

Lẹnu bi oṣu mẹfa sibi ni a ti ngbọ irohin iranṣẹ kan ni ilu Idọka; Irohin na pọ to bẹ gẹ ti ọpọlọpọ awọn ara ẹhin odi lọ njẹ anfani yi ju awa ti a ni anfani yi lọdọ wa. Nigbati Ọlọrun wo ara ilu Ileṣa bi a ti gọ to, lo dawa lọla Ẹmi mimọ yi. Ọlọrun da Ileṣa ati agbegbe rẹ lọla yi to pọ gan; a ko si mọ iru ogo nla ti Ọlọrun fi dawa lọla yi. A ko mọ iyi na

Bi aṣa owe awọn agba ti o sọ bayi pe "Ẹni to wa ni idi oru ki iru," o ya mi lẹnu wipe awọn ara Eko, Abẹokuta, Ibadan, Ijẹbu, Ilọrin, Oṣogbo, gbogbo wọn lo ti wa lati ilu wọn. ti Ọlọrun si nfi ọna rẹ han wọn; nwọn ki iyan enian ni ẹbọ owo, nwọn ki iyan enia ni ẹbọ ohunkohun, nṣe ni nwọn nsọ tẹlẹ. ninu Iwe Aposteli ori keji ẹsẹ ketadinlogun pe, "Yio si ṣe, ni ikẹhin ọjọ, emi yio tu ninu ẹmi mi sara enia gbogbo, ati ọmọ yin ọkunri ati ọmọ yin obirin, yio ma sọ tẹlẹ, awọn ọdọmọkunrin yio ma ri iran, awọn arugbo nyin yio ma la ala".

Nitorina ọrọ Ọlọrun ko ni sai ṣẹ. Nitorina kẹ wa fun igbala ẹmi nyin. Nitorina Ẹnyin ọmọ Ọlọrun, ẹ ma wa alafia, ki ẹ si ma lepa rẹ, nitori ogo ti Ọlọrun gbe kalẹ yi ki iṣe fun Serafu nikan bikoṣe ti gbogbo aiye. Ẹ ma jẹ ka fi oju kekere wo ogo ti Ọlọrun gbe kalẹ fun ilu Ileṣa ati agbegbe rẹ.

Awọn aboyun nbi wẹrẹ, awọn alaisan nri iwosan gba. Irohin ko to afojuba. Iwọ na tọ wo ki o si ri wipe rere ni Oluwa. Wa igbala fun ẹmi rẹ ki o ṣe rere fun ọmọ 'nikeji.

A si tun dupẹ lọwọ awọn Baba wa to ti nwa awọn enia ṣẹṣẹ ngbọ ni gẹgẹ bi mo ti ro, ki ẹ si tun ba mi wo iwe Iṣe Aposteli kanna ori ikeji ẹsẹ kejidinlogbọn ti o sọ wipe "Iwọ mu mi mọ ọna iye iwọ yio mu mi kun fun ayọ niwaju rẹ" Nitorina ẹ tara lati wa gbọ ki ẹ si mọ. Ninu iwe orin Mimọ sọ bayi pe "Ẹ fun ipe na kikan, ipe ihin rere ko dun jake jado leti gbogbo ẹda Ọlọrun, idasilẹ ti de pada, ẹlẹṣẹ pada" Ipe na ndun bayi ki ẹ si tẹti silẹ lati gbọ ipe. Ki olukuluku ji kuro ninu orun ọẹ, ki Ọlọrun Alaye maṣe jẹ ki a ṣegbe o Amin. Ki Oluwa ki ọna rẹye wa.

Irohin ko to afojuba ma si ṣe jẹ ki eṣu gba o niyanju o. Nitori ọrọ Oluwa wipe "Were ni agbelebu loju awọn a ma ṣegbe" ki Jesu ma ṣe ti yio ṣegbe" ki Jesu ma ṣe jẹ ka ṣegbe o amin. Ki ẹ si tun ba mi wo Iftihan ori 2 ẹsẹ 17: ẹniti o ba ni eti ki o gbọ ohun ti ẹmi nsọ fun awọn Ijọ

---

## Ẹ GBA MI LỌWỌ AKOTILETA OBIRIN

(Lati Ọwọ Daniel Ajumọbi, A. M 7 Iroye)

Jọwọ Olotu gba mi laye lati sọrọ lori akotileta Obirin to gb Eli. ni ọjọ kewa oṣu Novemba ninu ọdun to koja yi. Ni ọjọ ti a lọ gba, mo san ogun poun lati lọ gba iwe fun ọkọ rẹ Emmanuel Ju-egbe ni Oke-Iro. Nigbati mo gba wo tan. Kotu sọpe ki emi san poun marun ati Eli. poun marun; Kotu ni ti ko ba ri owo ko lọsi ẹwọn oṣu mẹta! Mo san owo na.

Ọkọ rẹ pe mi lẹjọ pe ọjọ na loyun, mo san poun mẹ sile mejila fun ọkọ rẹ. Nigbati ni Eli ni ki emi lọ pe ẹjọ, on yio fẹ mi, Mo pe ẹjọ poun marun, ojojumọ ni Eli wa ngba ṣile marun marun lọwọ mi, fun owo ọrọjẹ. Nigbati odi ọjọ kewa oṣu Marc i ọdun yi o pa gbogbo ẹru rẹ mọ: o to ọjọ kewa lẹhin yẹn, o ni ohun ko fẹ mi mọ.

Mo bẹ ẹnyin Ijọ ki ẹ ba mi gba owo mi lọwọ rẹ, owo na jẹ poun mọkanleladọta ati ṣile mẹjọ.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi o. Ẹ koni ri akotileta Obirin bẹ o.

---

## AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati sọ fun gbogbo awọn to nkọwe sinu Irawọ Obokun pe lati asiko yi lọ ko ni faye gba iwe ẹnikẹni ti ṣeata ko ẹnikẹni tabi ẹgbẹkẹgb Ṣugbọn aye wa fun ẹnikẹni ati sọ ọrọ lori eto ati iṣẹ ẹgbẹ tirẹ laipa ẹnikẹni lara:

ALABOJUTO

---



KANSẸLỌ A. T. BABAJIDE

On ni aṣoju igbimọ Ẹsa-Oke ninu igbimọ akopọ ti Ile Ijẹṣa. Ọgbẹni Ọla Ọlalẹyẹ ti Ebute Mẹta bẹ on ati awọn Kansẹlọ Ẹsa-Oke lati bojuto ilu Ẹsa-Oke.

---

## E KA NIPA IJOBA YIN

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitorina a ti nṣe orisiriṣi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa bi fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.

A fẹ aṣoju si ti Ileṣa.

A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe

A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.

A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Nitorina a nfẹ aṣoju ti yio ma fun wa ni irohin ati ti yio ma ta Irawọ Obokun ni awọn ilu wọnyi:- Ẹsa, Ibodi, Iperindo, Imẹsi Ile, Muroko, Itagun, Ipole, Igangan, Iṣẹ, Odo, Ilesa, Iwara, Erin Odo, Erin Oke, Ẹsa odo, New Ikeji, Oke Ikeji, Isaobi, Ijẹbujesa, Ekonl Ilerin, Ifẹ, Ibadan, Ofa, Ikirun, Iragbiji

# IJESHA RED CROSS WEEK

## 1st. — 6th. AUGUST 1955.

### Ẹ RAN AWỌN OLOTU RED GROSS LỌWỌ

Lati Ọwọ Ọgbẹni K. Y M Mackenzie, Ajẹlẹ ti Ipinlẹ Ijẹsa)

Kabiyesi, Oba Ajimọko ẹnyin Oloye Ile Ijẹsa ati ẹnyin Kansẹlọ pelu Ọrẹ jake jado Ile Ijẹsa; eyi ni lati fi si etigbọ yin pe ao fi odidi ọsẹ kan ṣe aṣẹdun fun Ẹgbẹ ti a npe ni Red Cross ni gbogbo ayika Ilẹ Ijẹsa. Aṣeyẹ na yio bẹrẹ ni ọjọ kini oṣu August de ọjọ kẹfa.

Ninu eto aṣeyẹ na, a fẹ ki olukuluku fi idawo ran Ẹgbẹ na lọwọ. Iye owo ti a nlẹ ki gbogbo Ipinlẹ Ijẹsa da, tabi ti a fẹ ki wọn da jẹ ni ẹgbẹran poun lọna kan ati abọ (£1,500). Ninu gbogbo igbokegbodo wa ni a ti fẹ ko owo na jọ.

Fun iyọrisi rira Ayo Orire ma ati ki ẹ le mọ oruko awọn to jẹ ti ẹ wo inu Irawọ Obokun ti ọjọ kejọ oṣu yi.

Ebun mẹrundinlọgọrin ni a ni silẹ fun Ayo Orire na. Owo ti a fira gbogbo ẹbun na jẹ adọjọ poun (£150). Ibi Ile idaraya to wa ni ẹnu odi ọna Oṣogbo ni wọn yio ti tayo orire na ni agogo mẹrin ọsẹ Jimọ ti ṣe ọjọ karun oṣu to mbọ. Gẹgẹbi ao tiṣe pin ẹbun ayo orire na ni wọnyi:

| IYE AW... TI YIO GBA ẸBUN | ẸBNN TI OLUKULUKU |
|---|---|
| 1 | Sewing Machine |
| 2 | Raleigh Bicycle (gents) |
| 1 | Rudge Bicycle (gents) |
| 1 | Gramophone |
| 1 | Radio |
| 1 | Tennis Racket |
| 1 | Tilley Lamp |
| 1 | Wrist Watch (gents) |
| 1 | Wrist Watch (ladies) |
| 1 | Pressure Stove |
| 10 | 6 yard length Cloth |
| 4 | Table-Cloths |
| 10 | Cartons 200 Pirate Cigarettes |
| 4 | Plastic Rain Coats |
| 4 | Blankets |
| 1 | Sauce-pan Set |
| 1 | 1 dozen dinner plates |
| 3 | Kettles (aluminium) |
| 3 | Frying Pans (aluminium) |
| 4 | Tins (Table Water) Biscuits |
| 4 | Galvanised buckets |
| 4 | Hurricane lanterns |
| 2 | Tins digestive biscuits |
| 6 | Whistling Kettles |
| 4 | Tea-pots (earthenware) |
| AROPỌ 75 Prizes | Aropọ Ebun £150 : 0 : 0d |

Awọn iwe Ayo Orire na ti wa lode fun tita. Ṣile kọkan ni iwe kọkan. Ẹ le ra iwe Ayo Orire na ra lati ọdọ awọn wọnyi:—

| LOCAL COUNCIL | | AWỌN AṢAJU |
|---|---|---|
| 1 Ifewara | ,, | Ọgbẹni Akinyẹmi |
| 2 Ifelodun | ,, | ,, M. B Komọlafe ati Abraham |
| 3 Oke-Bode | ,, | Oloye Loja Oke Bode |
| 4 Kiriji | ,, | Ọgbẹni Familuai ati Adegba |
| 5 Ibokun | ,, | ,, M. A. Adeyemi |
| 6 Ijẹbu Ijesha | ,, | Ọgbẹni Ijẹbu Jẹṣa ati Oriọke |
| 7 Ẹsa Oke | ,, | Loja Ẹsa Oke ati Ọgbẹni Babajide |
| 8 Ipetu Ijẹṣa | ,, | Ọgbẹni J. A Ọni ati Ogunjulugbe |
| 9 Irepodun | ,, | ,, S. Akinbẹgbẹ ati J. A Ajayi |
| 10 Muroko | ,, | Loja Isireyun ati O. S Obileye |
| 11 Ibodi | ,, | Ọgbẹni S. A Ojeti J. O George |
| 12 Atiletoro | ,, | Loja Oṣu ati E. Ayọọla, Adeyẹye |
| 13 Oshun | ,, | Oṣunloye Ọṣun ati Lawanson |
| 14 Itagunmodi | ,, | Loyin Itagunmọdi ati Fapohunda |
| 15 Aiyepeju | ,, | Aloke ti Ilọbu Kansẹlọ Ọladare |
| 16 Erin | ,, | Ọgbẹni J. B Oshunmakinde |
| 17 Iwara | ,, | Oloye Lumi |
| 18 Isa Obi | ,, | Ọgbẹni S. Bọwaji |
| 19 Ilupeju | ,, | ,, ,, S. Makinwa |
| 20 Aiyegunlẹ | ,, | S.O Thomson, E. A Fajẹmisni |

Eyi to pọju ninu owo ti aba ri kojọ ninu Igboro Ilẹṣa ni ao na lori ile Itọjuto alafia ilu (Welfare Centre) ti a kọ si Ilẹṣa ti ao si ṣi laipẹ. Awọn owo ti aba ri kojọ lati akamọ Local Council kọkan ni ao pin fun nina fun wọn lori bi wọn ba ti dawo to lati akamọ kọkan.

Awọn owo be ti aba ri kojọ ni ao fira egbogi ati irin iṣẹ ilera fun ile Igbẹgbogi, ile igbọbi ati awọn ile iwe gbogbo.

Ao ṣi office kekere kan fun eto iwadi lori gbogbo nkan wonyi lati ọjọ Monde, ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi (July 1955) ni ibi iṣẹ Ijọba Ijẹṣa. Ni office na, ẹ le ri iwe Ayo Orire na ra, ẹ si le bere fun ohunkohun lori awọn eto to wa fun aṣeyẹ ọsẹ Red Cross na.

Pẹlu iyọnda Ẹgbẹ iṣowo U. A' C. Ilẹṣa, ao ko gbogbo awọn ẹbun Ayọ Orire na sinu yara ọnidingi kan ni Kingsway Store fun ẹnikẹni lati ri lati ọjọ Kejidinlogun oṣu yi si ọjọ Jimọ ti iṣe ọjọ karun oṣu August.

## RAFFLE DRAW

**You are hereby notified that owing to the late arrival of the full quota of Raffle Tickets, the draw for prizes has been postponed from Friday 5th. August to Friday 19th. August 1955. The Draw will take place at the same place on 19th. August at Council Recriation Ground Oshogbo Road Ilesha at 4 p.m. on 19th. August.**

**You are notified that a correct list of winning ticket numbers will appear in Irawo Obokun issue of Monday 22nd. August 1955.**

## ERIN LOCAL COUNCIL

Applications are invited from suitably qualified candidates for filling the vacant post of a Secretary, Treasurer, to the Erin Local Council.

**Qualification**— Applicant must be literate in English and must be at least Middle IV, must have a good knowledge of office routine, able to type at a minimum speed of 100 words a minute, and have a good organising ability.

**Salary:**— According to experience and qualification.

**Method of Application:**— Application which must be made in applicant's own handwritinig, must give details of age, place of birth, previous experience, and be accompianied with copies of testmonials, should be submited to reach the Chairman, Erin Local Council, c/o The Modern School, Ipetu—Ijesha not later than Monday, 8th. August, 1955.

Sgd.

**J. B. Oshunmakinde**
CHAIRMAN, E. L. C.

## WANTED

A Full Time Secretary for Aiyepeju Local Council to take appointment immediately. Applicants must have Class Six or at least Class Four Middle Certificate

Must also have a knowledge of typing and office routine. All applications should be directed to the Chairman, Aiyepeju Local Counil, P. O. Box 49, Ilesha, reaching him not later than August 26, 1955.

EBN. I. ALO.
Ag. Secretary.

## WO AWON NOMBA TO JAYO ORIRE NINU IWE TI 22/8/55

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B149 Okesha Street, Ilesha 1 ..1 — 55